# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kejilelogun: Osu Karun Ojo Kejidinlogbon, 2017**

**Akori oro: Lo Ojo Isinmi ni mimo** –Apa Kini

**Eko kika: Deuteronomi 5: 1-14**

## Afihan

Ojo-isinmi je ojo keje ninu ose, eyiti awon onigbagbo ma nlo lati sinmi ati lati josin fun Olorun. Eyi je ojo ti awon elesin ki ilo si ibi-ise. Lotito awon omo Israeli ti ise eya Ju, nwon se ojo-abameta ni ojo-isinmi tiwon, gegebi kalenda awon Ju: nigbati awon kristiani se ojo-Oluwa ni ojo-isinmi tiwon, gegebi kalenda awon oyinbo. Ojokojo ti o ba gba gegebi ojo keje ninu ose, eyi ni yio je ojo-isinmi tire.

Ojo-isinmi je ojo mimo ti a ni lati bowo fun u, nitoripe ni ojo yi ni Olorun Olodumare sinmi kuro ninu awon ise re ti o fi da aiye on orun ati ohun gbogbo ti ibe ninu won. Bibeli wipe "Ni ijo keje Olorun si pari ise re ti o ti nse; o si sinmi ni ijo keje kuro ninu ise re gbogbo ti o ti nse. Olorun si **busi** ijo keje, o si **ya a si mimo**; nitoripe, ninu re li o sinmi kuro ninu ise re gbogbo ti o ti bere si ise" **Genesisi 2: 2-3**. Nitorina, o ni lati pa ojo-iyasoto Olorun mo, ki o si lo ni mimo ati fun itesiwaju ise Oluwa.

Ojo-isinmi ki ise ojo ti a nrin kiri, lati ko owo jo nitori aisan-kaisan, beni ki ise ojo ti a gbodo lo fun ere-idaraya, tabi lati lo sin gbese owo ti awon enia je wa. Awon kristiani ko gbodo gbagbe ase ati itoni Oluwa Olorun nwon, Sugbon ki nwon "Ranti ojo isinmi, lati ya a simimo. Ojo mefa ni iwo o sise, ti iwo o si se ise re gbogbo: Sugbon ojo keje li ojo isinmi Oluwa Olorun re: ninu re iwo ko gbodo se isekise kan, iwo, ati awon omo re okunrin, ati omo re obinrin, omo-odo re okunrin, ati omo-odo re obinrin, ati ohun-osin re, ati alejo re ti mbe ninu ibode re" **Eksodu 20: 8-10.** Niwon igbati o je wipe ojo mefa ni a yasoto larin ose fun o lati se ojuse ati ise re; ya ojo keje simimo fun Oluwa, nipa sisinmi ati jijosin fun Oluwa ni ojo yi.

Ojo isinmi se iyebiye si Olorun, ati nitoripe ojo yi se pataki niwaju Oga-ogo ni o muki o se ni okan lara awon opo-ofin re; (ti opo enia ma npe ni ofin-mewa Oluwa) **Deuteronomi 5: 13-14**. Ri daju wipe o ko sun orun asunju, sugbon o koko lo si ile Oluwa lati josin ni ojo-isinmi, ki o to wa tesiwaju lati se awon ohun

ti ara re. Nitorina, pa ojo-isinmi mo, yasoto fun Oluwa, bowo fun ojo yi, ki o si lo ni mimo; gegebi Oluwa Olorun re ti pa o lase **Deuteronomi 5: 12.**

## Iru orisi ojo isinmi ti o wa

Ojo isinmi orisi meta ni o wa, ti awon oruko won si je: Ojo isinmi Oluwa, Ojo isetutu ati isinmi olodun keje.

**Ojo isinmi Oluwa**: Ijo mefa ni ki a se ise: sugbon ni ojo keje **gbogbo-ose** li ojo isinmi, apejo mimo; enyin ko gbodo se ise kan ninu re: nitoripe ojo-isinmi Oluwa ni ninu ibujoko nyin gbogbo **Lefitiku 23: 3.**

**Ojo isetutu:** Ojo kewa ninu osu keje odun, kristiani ni lati pon okan nwon loju, beni nwon ko si gbodo se isekise kan ni ojo yi. Alufa yio se etutu lati we won mo, ki nwon le mo kuro ninu gbogbo ese won niwaju Oluwa. Ojo yi je ojo isinmi, ki nwon si pon okan won loju nipa awe. Ilana ni titilai **Lefitiku 16: 29-31, 23: 26-32.** Ni ode-oni awon ile-ijosin ti fi "awe ogoji ojo nigba ijiya Kristi" ropo "Ojo isetutu" nitori iku Oluwa lori igi agbelebu **Colossians 1: 14, Hebrews 9: 12.**

**Isinmi olodun keje:** Odun mefa ni iwo o fi gbin oko re, odun mefa ni iwo o si fi rewo ogba-ajara re, ti iwo o si ko eso re jo; Sugbon odun keje ki o jasi igba isinmi fun ile na, isinmi fun Oluwa: iwo ko gbodo gbin oko re, beni iwo ko gbodo rewo ogba-ajara re **Lefitiku 25: 2-4; Eksodu 23: 10-11.**

Ohun ti awon ojo wonyi ati odun yi ni lapapo ni isinmi ati apejo mimo lati josin fun Oluwa. Ao soro lori ojo isinmi nikan ni pato ninu eko yi.

## Pataki tabi iwulo ojo isinmi Oluwa

Opolopo ni iwulo ati pataki ojo-isinmi ti a ko sinu Bibeli, beni ao si se ayewo won..

**Olorun fi apere le'le**: Olorun ninu akainiye anu re, ma nfi apere le'le fun awa eda-enia lati tele. Iwe mimo wipe "Nitori ni ijo mefa li Oluwa da orun on aiye, okun ati ohun gbogbo ti mbe ninu won, o si sinmi ni ijo keje: nitorina li Oluwa se busi ijo keje, o si ya a si mimo" **Eksodu 20: 11.** Bi Olorun ba le sinmi ni ojo isinmi, iwo na nilo lati sinmi. Bi Olorun ba busi ojo isinmi, ti o si ya a si mimo, iwo na ni lati lo ojo isinmi ni mimo, ki o si josin fun Oluwa eleda re.

**Awa enia nilo itura:** Enikeni ti o ba nsise bi owo-agogo lai-sinmi le padanu emi re, tabi ki o se akoba fun ilera ago-ara re. Nitori idi eyi ni Oluwa se fun wa ni ojo-isinmi, ki a ba le sinmi, ki a si tu ara wa lara. A kowe re wipe "Ijo mefa ni iwo o se ise re, ni ijo keje ki iwo ki o sinmi: ki akomalu re, ati ketekete re ki o le sinmi, ki a le tu omo iransebinrin re ati alejo lara" **Eksodu 23: 12.** Awon enia ninu aiye loni nse awokose Olorun nipa gbigba isinmi ni enu-ise tabi ni ile-eko nwon, ki nwon ba le tu ara won lara. Bi o ba nfe ki ara re mokun, ki o si ji pepe, o ni lati sinmi; bi o ba nfe itura, o ni lati pa ojo isinmi mo.

**O je ami larin Olorun ati awa kristiani**: Ojo-isinmi je ami majemu larin Olorun ati awon onigbagbo ni gbogbo ojo aiye nwon. Awon kristiani ni lati pa ojo isinmi mo nitoripe ami ni larin Olorun ati awon olufokansin lati irandiran nwon; ki gbogbo enia le mo wipe Oluwa ni o ya won soto funrare, ti o si nya nwon si mimo **Eksodu 31: 13.** Awon enia ti npa ojo isinmi mo, nfi ami-igboran ati ami-iyasoto han ninu aiye nwon.

**Imuse oro Olorun:** Bi a ba se akiyesi adura-Oluwa, ese kan ninu adura yi wipe, "Ife tire ni ki a se, bi ti orun, beni li aiye" **Matteu 6: 9-13.** Lati se ife Olorun ni aiye, bi nwon ti ise li orun; a ni lati pa ojo isinmi Oluwa mo, gegebi Olorun ati awon orun ti ipa ojo mimo yi mo. "Nitori o ti so nibikan niti ojo keje bayi pe, Olorun si sinmi ni ijo keje kuro ninu ise re gbogbo" **Heberu 4: 4.**o Fun oro Oluwa lati wasi imuse ninu aiye wa; a ni lati bowo fun ojo isinmi, ki a sinmi ni ojo keje: ki a si josin fun Eleda wa.

**Majemu aiyeraye ni ojo isinmi:** Olorun fi ojo-isinmi fun awon onigbagbo gegebi adehun ti ko se yipada larin on ati awon kristiani. Nitorina, li awon kristiani se gbodo ma pa ojo isinmi mo, ki nwon si ma kiyesi ojo isinmi lati irandiran won, fun majemu titilai **Eksodu 31: 16.** Niwon igbati a ni majemu aiyeraye pelu Olorun, etise ti e ko fi jeki a gbe laruge, ki a si ma pa a mo titilai.

## Olorun ti se ipese fun ojo isinmi

Ki Olorun to wipe ki a ma sise fun ojo mefa, ki a si sinmi ni ojo keje; Oluwa ti se ipese awon ohun ti a nilo ni ojo keje nigbati a koni sise, bikose ki a sinmi. Olorun mo wipe ni ojo keje, yala a se ise tabi a ko se ise, a ni lati jeun: nitorina, Oluwa ti seto akainiye nkan ti yio mu itura ati idera bawa; lati gbo bukata aiye wa ni ojo keje.

Olorun se afihan eyi, nigbati o nfi **manna** bo awon omo Israeli ni aginju. Ni ojo kefa, Mose so fun awon omo Israeli ki nwon ko ilopo-meji **manna** ni ojo kefa gegebi ase Oluwa: nitoripe, ojo keje ni ojo-isinmi Oluwa; **manna** ko ni jabo lati orun ni ojo keje, niwon igbati Olorun funrare yio ma sinmi. O si se li ojo keje awon kan ninu awon omo Israeli jade lo lati ko **manna**, nwon ko si ri nkankan. Awon omo Israeli si je **manna** ti o siku sile lati ojo kefa ni ojo keje; **manna** ti o siku sile yi ko si run, beni ko yo idin, nitoripe Olorun fun nwon ni ore-ofe, o si pese fun nwon nitori ojo-isinmi **Eksodu 16: 22-30.**

Bibeli wipe, "Oju gbogbo enia nwo o; iwo si fun won li onje won li akoko re" **Orin Dafidi 145: 15.** Bi Olorun ba npese fun gbogbo eda alaaye ti won gbekele, nipa fifun won ni onje ni akoko, se Oluwa ki yio pese onje ati ohun gbogbo fun awon ti ipa ojo-isinmi ti ise majemu aiyeraye re mo?

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Ketalelogun: Osu Kefa Ojo Kerin, 2017**

**Akori Oro: Lo ojo isinmi ni mimo** –Apa Keji

**Eko kika: Deuteronomi 5: 1-14**

Eko yi yio tesiwaju nigbati ao so di mi'mo fun awon enia wipe ojo isinmi ni a npe ni ojo Oluwa.

### Ojo Oluwa

Otito ti enia ko le ko jiyan ni pe, Jesu Kristi ni Oluwa ojo isinmi. A kowe re wipe "Nitori Omo-enia je Oluwa ojo isinmi" **Matteu 12: 8, Marku 2: 28, Luku 6: 5.** Niwon igbati Kristi ti je Oluwa ojo isinmi, lati isisiyi lo, ao ma pe ojo-isinmi ni ojo Oluwa; beni awon kristiani gbodo ma pe ojo isinmi ni ojo Oluwa.

A ni lati mo wipe a da ojo isinmi fun anfani eda-enia ni. Olorun da ojo isinmi fun awa omo-enia ki a le sinmi ninu re ni. Oluwa da ojo-isinmi ni koko, fun lilo awa enia, ki isi se wipe o da enia nitori ojo-isinmi. Bibeli wipe "A da ojo isinmi nitori enia, a ko da enia nitori ojo isinmi" **Marku 2: 27.** A da ojo isinmi fun enia, nitorina, e jeki a pa ojo yi mo, ki a si lo ni mimo.

Aposteli Johannu lo ojo Oluwa ni ona ti o se itewogba si Olorun, beni o ri iran-orun eyiti o se anfani fun awa eda-enia; ti o si fi oye ye gbogbo omo adari-hurun titi di oni yi **Ifihan 1: 9-20.** Bi iwo na ba lo ojo isinmi ni ona ti o se itewogba, ao fi o pa 'itu-meje, yaya-mefa' ninu aiye: besini ao lo o fun itunu gbogbo eda enia.

### Siso Ojo Oluwa di aimo

Kristiani, kini Oluwa se lodi si nyin? Ona wo ni o gba lati di ajaga ru nyin? Kini Olorun se ti o mu ki e ya kuro niwaju re? Bawo ni o se da nyin li agara, ti ko fi jeki e pa ojo-isinmi mo, ti e kosi lo ni mimo? Olorun nfe lati mo idi ti suuru nyin fi tuka/tan? **Mika 6: 3.** Bi Olorun ko ba se ohun kan lodi si nyin, ti ko si da nyin li agara, e pada si odo Eleda nyin ki e si ba a laja. E ni lati gboro si ase re, nipa sise ise fun ojo mefa, ki e si sinmi ni ojo keje, ti ise ojo Oluwa.

**Awon enia ti nwon wa ni ipo alase:** Ogoro enia ti nwon wa ni ipo alase, ni won ngan awon ohun mimo Oluwa, ti won ko si bowo fun ojo isinmi. Opo ninu

nwon ni ki ipa ojo Oluwa mo, beni nwon ki ilo ni mimo. Eyiti o fi yeki nwon wa ni ile-ijosin niwaju Olorun ni ojo-Oluwa: oniruru ipade ni nwon yio ma se. Nwon yio ma ngbero ibi si omonikeji, nwon o si ma mu ise buburu won se ni ojo-mimo yi. Aimoye ninu nwon yio ma ti apeje kan de omiran ni ojo Oluwa. **Esekieli 22: 6-8.** E dekun gbogbo iwa-buburu yi, eyiti o le mu Oluwa binu sin yin: ki e si se atunse, nipa lilo ojo Oluwa niwaju Eleda nyin.

**Awon alufa ati awon asiwaju ninu esin**: Akainiye awon alufa ati awon asiwaju ninu esin igbagbo ni nwon nte ofin Oluwa loju mole, ti nwon kosi ka ofin Olorun si. Awon wonyi ma ntabuku ba awon ohun mimo Oluwa, nitori owo ati ebun. Opo ninu awon wonyi ni nwon ma ngan ofin Oluwa, ti won si nba tempili mimo re je. Iwe mimo wipe, " Awon alufa re ti ru ofin mi, nwon si fi so ohun mimo mi di alailowo: nwon ko fi iyato sarin ohun mimo ati alailowo, beni nwon ko fi iyato han larin ohun aimo ati mimo, nwon si ti fi oju won pamo kuro li ojo isinmi mi, mo si di eni ailowo larin won" **Esekieli 22: 26.** E mase dabi awon alufa ati awon asiwaju esin wonyi, ti nwon ko so otito jade nitori ere; nwon di oju si iwa-ibaje ti awon olola nhu, nitori ohun asan aiye yi.

**Opo enia ni nso tempili di aimo:** Opo kristiani ni nwon nso tempili mimo Oluwa di aimo; tempili ti awon angeli nlo pelu iwariri ati owo, ni awon kristiani ko bowo fun:

- Akainiye awon kristiani ni nwon nba ara won lopo, ti won ki isi we, beni won ki isi tabi ya ara won simimo, ki won to lo si ile-ijosin.
- Ogoro kristiani ni nwon ma nmu oti, ki won to wasi iwaju Olorun.
- Opo kristiani ni nwon nwa si ile-Olorun lati wa se agbere tabi pansaga.
- Awon miran nwa si ile-ijosin lati wa lu awon enia ni jibiti, tabi lati wa se kara-kata ni ile-mimo. A kowe re wipe "Eyi ni nwon si se si mi; nwon ti ba ibi mimo mi je li ojo kanna, nwon so ojo isinmi di ailowo" **Ezekiel 23: 38.** Iru awon enia wonyi ni lati siwo awon iwa-buburu yi, ki nwon maba jebi esun meji ni iwaju Olorun.

Opo kristiani ni nwon nni idapo pelu awon okunkun, ki won to tesiwaju losi ile-ijosin lati ni idapo pelu Olorun. Iru awon enia wonyi ntan ara won ni, nitoripe Olorun ko le ni idapo pelu nwon. Irufe awon kristiani wonyi ma nko orin ni ile Yoruba wipe "Awa o so'ro ile wa o (2ce) igbagbo o pe kawa ma so'ro, awa o so'ro ile wa o." Awon onigbagbo ni lati yi orin na pada si "Me le (3ce) sin Oluwa pelu mamoni o." Bibeli wipe "Nitoripe igbati nwon pa awon omo won

fun orisa won, nigbana ni nwon wa ni ijo kanna si ibi mimo mi, lati so o di alailowo; si kiye si i, bayi ni nwon se larin ile mi." **Esekieli 23: 39.** Enikeni ti o ti so ara re di alaimo nipa rirubo si orisa tabi nipa idapo pelu awon okunkun, ko gbodo wa sinu tempili Olorun lati ba a je. Opo awon 'kristiani-alafenuje' ti nwon je agbode-gba ati agbase-se, lati wa kun omo-egbe fun awon ijoba orun-apadi ni lati dekun ni kiakia; ki idajo Olorun to wasi ori won.

Awon 'kristiani alafenuje' ti nwon nwa si iwaju Olorun, ti won je omo-egbe oso tabi aje, pelu awon ogboni ati awon omo-egbe imule, ni lati kuro ninu egbe buburu yi; ki nwon ronupiwada lododo, ki ibinu gbigbona Olorun maba wasi ori won.

**Kristiani ko gbodo pa esin je:** Awon kristiani ko gbodo pa esin je, ni igbakugba ti esin ba wa ni ile-ijosin; paapa-julo esin ojo Oluwa. Kosi eniti o mo ojo ibewo re, nigbati Oluwa yio ran awon angeli, ki won sokale lati wa yanju isoro aiye re. Ranti ese Bibeli ti o wipe "Ki a ma ko ipejopo ara wa sile, gege bi asa awon elomiran; sugbon ki a ma gba ara eni niyanju; pelupelu bi enyin ti ri pe ojo ni nsunmo etile" **Heberu 10: 25.** Nitorina, Kristiani e mase ainani awon isin-ipejopo tabi ipade-adura; pataki-julo isin ojo Oluwa. E mase se atunwi-asan wipe "emi na ngbadura ninu ile mi" sugbon e lo darapo mo apejopo awon eni-mimo ni ile-ijosin.

## Kristi lo si tempili ni ojo isinmi

Jesu Kristi fi apere le ile, bi o ti ye ki enia lo ojo Oluwa ni ona ti o to. Ni aimoye igba ni o lo si tempili ni ojo Oluwa lati lo se ise Baba re. Nitorina, gbogbo kristiani ni lati losi ile-ijosin ni ojo Oluwa.

Jesu ati awon omo-ehin re lo si tempili ni ojo Oluwa, o si nko awon enia ni oro Olorun **Marku 1: 21.** Ni ojo kan, Jesu lo sinu sinagogu li ojo Oluwa, o si ka iwe-mimo **Luku 4: 16-18.** Bi iwo na ba lo si ile-ijosin ni ojo Oluwa, ti o ba nkoni tabi wasu oro Olorun, oro na yio se ibapade aiye awon enia. Awon keferi ni agbegbe ile-ijosin nyin, yio si bebe pe ki o tunbo so opo oro-Olorun (Ihin-rere) yi fun nwon: ogoro awon keferi yi yio si ronupiwada, nwon yio si fi aiye won fun Olorun **Ise awon aposteli 13: 42.** Bi o ba fe je ohun-elo ola, o ni lati kede Ihinrere, ki o si jere okan sinu ijoba Olorun.

Se afarawe Jesu Kristi nipa sise rere, ati lilo si ile-ijosin ni ojo Oluwa **Marku 6: 1-2.**

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Ose Kerinlelogun: Osu Kefa Ojo Kokanla, 2017

## Akori Oro: Lo ojo isinmi ni mimo –Apa Keta

## Eko kika: Deuteronomi 5: 1-14

Eko yi ntesiwaju lori awon ofin Oluwa ti o diromo ojo isinmi. Gegebi a ti so tele wipe ojo isinmi ni o nje ojo Oluwa. Ao ma lo eyikeyi ti o ba tewalorun ninu won.

### Awon ofin Olorun

Lotito, ofin Oluwa ni o wipe "li ogun oju wa ni awa yio ma jeun, titi awa o fi pada si ile…." **Genesisi 3: 19.** Ko leto lati sise ni ojo isinmi, ninu eyiti Olorun funrare sinmi kuro ninu ise re; nitoripe majemu ni ojo isinmi je larin Olorun ati awa onigbagbo. Nitorina, pa ojo Oluwa mo, ki o si lo ni mimo, mase ba majemu Olorun je, sugbon bowo fun majemu re ni igbagbogbo.

**E se afarawe Nehemiah:** Bi o ko ba fi lilo si ile-ijosin lati lo josin fun Olorun se ohun akoko ni ojo Oluwa, isekise ti enia ba se ko le gberu: bi enia ba si ri owo ninu ise ti o se ni ojo yi, iru eni be koni le na owo na ni ona ti o dara-julo, nitoripe o ti tapa si ofin Olorun, beni ko si pa majemu re mo.

E safarawe Nehemiah, e mase jeki tita tabi rira tabi isekise sele ni ojo Oluwa, ayafi bi e ba koko lo si ile-ijosin lati lo josin fun Oluwa. Bi awon onisowo ba mu oja wa ni ojo isinmi, e mase gba ni owo nwon **Nehemiah 10:31.** Ojuse wa ni lati kilo fun awon enia ti nwon nta ti nwon si nra ni ojo Oluwa, ti nwon ko si koko lo si ile-ijosin. Bi iru awon enia be ko ba fetisi ikilo, e ni lati ba won wi gidigidi, ki e ba le tu ibinu-Olorun ti a ti pese sile fun awon enia ti o ba ojo-isinmi je, loju. **Nehemiah 13: 15-19.** Lati isisiyi lo, se ipinnu lati koko josin fun Olorun ni ojo isinmi, ki o to ma se awon ise-oojo re.

**Pa ojo isinmi mo, ki o si bowo fun awon obi re:** Ojuse awon kristiani ni lati bowo fun awon obi won, ki nwon si pa ojo isinmi mo. Bi o ba pa ojo isinmi mo, sugbon ti o se alai-bowo fun awon obi re, o ti ru ofin Oluwa. Fun enia lati ri ere, pipa ojo isinmi mo gba, o ni lati bowo fun awon obi re. A ko ninu Bibeli wipe " Ki olukuluku nyin ki o beru iya re ati baba re, ki o si ma pa ojo isinmi mi mo; Emi li Oluwa Olorun nyin" **Lefitiku 19: 3.**

**Pa ojo isinmi mo, ki o si bowo fun ile Oluwa:** Awon kristiani ti nwon npa ojo Oluwa mo, nipa lilo si ile-ijosin lati lo josin fun Oluwa Olorun, ko gbodo se ohun egbin tabi se alaibowo fun ile Oluwa. Mimu ofin Oluwa se, nipa pipa ojo isinmi mo, ki ise awijare fun won, lati so ile Oluwa di ohun eeri tabi lati lo ni ona ti ko ye. A kowe re wipe "Ki enyin ki o si ma pa ojo isinmi mi mo, ki enyin ki o si bowo fun ibi mimo mi: Emi li Oluwa" **Lefitiku 19: 30; 26: 2.** Kristiani, e kiyesara ni igbakugba ti e ba wa ni ile-ijosin, e mase si i lo; beni e ko gbodo se alai-bowo fun ibi mimo Oluwa.

## Awon iyorisi ai-pa ojo isinmi mo

Sise ise ni ojo-isinmi, je okan lara awon arekereke ti Satani ma nlo lati tan awon kristiani, ki won le subu sinu ese, ki won si le kose niwaju Oluwa. Idanwo yi je ohun ti o tankale, nitori afikun-owo ti won nsan, fun awon ti o ba sise ni ojo isinmi, ati owo ti awon onisowo ti o ba si ilekun ile-itaja won ni ojo isinmi nri. E mase se alai-nani awon iyorisi ati isoro ti yio de ba gbogbo eniti o ba ba ojo-isinmi Oluwa je.

**Ibanuje nla nduro de nwon ni ikorita:** Opolopo kristiani lero wipe awon je ologbon, eyiti o fi yeki won lo josin fun Olorun ni ojo Oluwa, awon wonyi yio lo si ibi-ise nwon, nitori afikun-owo ti won yio gba. Iru awon enia wonyi je asiwere, nitoripe won nfi ogbon-ara ti ise asiwere niwaju Olorun, lati fi se idajo awon nkan Oluwa ti ise ti emi. Iwe mimo wipe "Nitori ogbon aiye yi were ni lodo Olorun. Nitori a ti ko pe, Eniti o mu awon ologbon ninu arekereke won" **1 Corinthians 3: 19.** Iru awon eya wonyi ki ise ologbon bikose asiwere.

Ibanuje-nla nduro de enikeni ti o lo si ibi-ise ni ojo-isinmi, ni alai-lo si ile-ijosin; nitoripe Satani yio gbe koto agbana siwaju nwon, eyiti yio lo lati gba gbogbo owo-ise ti won ri, nipa biba ojo-isinmi je. Bibeli wipe "Egbe ni fun awon ti nwon gbon li oju ara won, ti nwon si mo oye li oju ara won!" **Isaiah 5: 21.** Sise ise ni ojo Oluwa, ni ai-lo si ile-ijosin, ki ise ogbon bikose were. Nitorina, sa fun iwa buburu yi.

**Ao ke nwon kuro:** Okan lara awon iyorisi biba ojo Oluwa je ni pe, ao ke iru awon enia na kuro, ninu awujo awon asayan-enia Olorun. Enikeni ti o ba se isekise ni ojo Oluwa ni ao ke kuro ni awujo awon eni-mimo **Eksodu 31: 14.** Opo kristiani ma nlero wipe, bi awon ba tesiwaju lati ma sise ni ojo-isinmi, ti awon si

di olola enia; ao gba nwon pada si awujo awon enia Olorun; sugbon awon wonyi ti kuna. Bi a tile gba awon wonyi pada si ile ijosin , won ki yio le jogun ijoba orun; ayafi ti nwon ba ronupiwada, ti nwon si beresi pa ojo-isinmi mo.

Akainiye kristiani ni nwon ma nse ise-asemoju, ti o je wipe, nigbati yio ba fi di ojo isinmi, aare yio ti mu nwon, debipe won ko ni le fi okan dogba pelu isin ninu ile Oluwa. Bi isin ba pe e, ogoro kristiani ni ki ini suuru, ki esin pari ki nwon to kuro ni iwaju Olorun. Iru awon enia wonyi gbodo se ayipada akoko-ise won, bi aye ba wa fun iru igbese yi, tabi ki nwon ma ni suuru ki isin pari.

Iru awon enia wonyi gbodo ranti ese Bibeli ti o wipe ".. ni iwaju Oluwa li ekun ayo wa.." **<u>Orin Dafidi 16: 11.</u>**

**<u>Ao pa nwon run:</u>** Ijo mefa ni ki a se ise; sugbon li ojo keje li ojo isinmi, mimo ni si Oluwa: enikeni ti o ba se isekise li ojo isinmi, on li ao si pa nitoto **<u>Eksodu 31: 15; 35: 2, Numeri 15: 32-35.</u>** Awon kristiani le ma so wipe iru nkan yi ko le sele, li akoko tabi igba yi; otito ni, **<u>sugbon Olorun ni agbara lati mu ki gbogbo awon enia ti o ba ojo-isinmi je, di oku ninu emi dipo kiku nipa ti ara.</u>** Nitorina, awon kristiani ko gbodo ko iwa awon keferi, ti nwon nba ojo isinmi je.

**<u>Ikilo lati odo Oluwa:</u>** Olorun kilo fun awon omo Israeli wipe, "Bayi li Oluwa wi, E kiyesara li okan nyin, ki e mase ru eru li ojo isinmi, beni ki e ma si se mu u wa ninu enu-bode Jerusalemu: Beni ki e ma si se gbe eru jade kuro ninu ile nyin li ojo isinmi, beni ki e ma se isekise, sugbon ki e ya ojo isinmi si mimo, gege bi mo ti pase fun awon baba nyin" **<u>Jeremiah 17: 21-22.</u>** Kristiani, e fiyesi ikilo Oluwa, ki e si wa Oluwa Olorun ni ojo isinmi (ojo Oluwa): ojo ti Olorun bukun, ti o si ya simimo. E kepe Oluwa larin isin-apejopo, ni ojo Oluwa: beni yio si da nyin lohun, nitoripe o wa nitosi, o si ti setan lati yanju awon isoro ati wahala nyin. A kowe re wipe, "E wa Oluwa nigbati e le ri i, e pe e, nigbati o wa nitosi" **<u>Isaiah 55: 6.</u> Olorun nduro de o, ninu ile-ijosin , ni ojo isinmi: nitorina mase padanu anfani-nla.**

**<u>Ao fi ina sun ile-ise nwon:</u>** Olorun yio fi ina sun awon ile-ise ati isura gbogbo awon enia ti ko fiyesi ikilo Oluwa, lati bowo fun ojo isinmi. Olorun yio lo ina-ajooku, lati pa awon ohun-ini nwon run, nitoripe nwon ko pa ojo isinmi mo, sugbon, won ntesiwaju lati so o di ailowo, nipa sise ise ni ojo Oluwa **<u>Jeremiah 17: 27.</u>** Bi o ko ba fe ki ina sun awon isura re nipa ti ara ati emi, dekun ise sise ni ojo isinmi.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Karundinlogbon: Osu Kefa Ojo Kejidinlogun, 2017**

**Akori Oro: Lo Ojo Isinmi ni mimo** –Apa Kerin

**Eko kika: Deuteronomi 5: 1-14**

Eko yi ntesiwaju nigbati ao soro nipa awon anfani ti a ti pese sile fun awon enia ti nwon ba pa ojo isinmi mo.

**Awon anfani**

Awon kristiani ni lati mo wipe isekise ti o ba se ati iye wakati yowu ti o le lo lenu ise re ko je nkankan, niwon igbati o ba ti pa ojo isinmi mo, ao bukun fun o. Bibeli fi idi re mule wipe Ibukun Oluwa ni imu ni ila, ki isi ifi laala pelu re **Owe 10: 22.** Bi o ba fe ni ola ti koni ibanuje ati abamo, pa ojo isinmi Oluwa mo.

**Ibukun ni fun eniti ti o pa ojo isinmi mo, ti ko si ba a je:** Awon kristiani ti Olorun nfe lati mulo si ipo giga ati ipo olokiki ninu aiye, bi nwon ko ba yege nigbati a ba danwon wo pelu awon ipo kekeke, nje Olorun yio yara lati fi nwon se alakoso awon ohun-nla ninu ara ati ninu emi? Niwon igbati won je alakoso awon ipo kekere, ti nwon ko ri aye lati sin Oluwa, ti kosi aye fun nwon lati ya ojo isinmi si mimo. Se o ko mo wipe Oluwa yio gbe owo le igbega ati itesiwaju iru awon enia wonyi, tabi ki o fifun aladugbo won ti o san ju won lo.

A kowe re wipe "Alabukun ni fun okunrin na ti o se eyi, ati fun omo enia ti o di i mu: ti o pa ojo isinmi mo laiso o di aimo; ti o si pa owo re mo kuro ni sise ibi" **Isaiah 56: 2.** Bi o ba fe ki ibukun agbayanu Oluwa wasi ori re, pa ojo isinmi mo lododo. Mase so ojo isinmi di ailowo tabi eleeri, beni ki o dekun sise ibi.

**Olorun yio fun o ni oruko ainipekun:** Olorun wa ki ise ojusaju enia, ni Bibeli wi **Romu 2: 11.** Nitorina, enikeni lati inu eyakeya, okunrin tabi obinrin, iru awo-kawo ti o le je, arugbo tabi omidan, ti o ba ti nse awon ohun ti inu Oluwa dun si; ti o si fi aiye re fun Oluwa ni pipe yio di eni-ibukun. Awon enia ti nwon npa ojo isinmi Oluwa mo, ti nwon si se olooto si majemu Oluwa, yio ma bisi won o si ma re si.

Olorun yio gbe ohun-iranti kan kale ninu tempili mimo re, nibiti ao ko oruko iru awon enia wonyi si; ni ona ti yio jeki o daraju ki enia bi opolopo omo lo,

nitori ohun-iranti yi yio wa titi-lai. Olorun yio fi ipo kan fun won ni ile re ati ninu odi re, ati oruko ti o dara ju ti awon omo-kunrin ati omo-binrin lo: Oluwa yio si fi oruko ainipekun fun won, ti a ki yio ke kuro, sugbon ti yio wa titi-lai **Isaiah 56: 3-5.** Bi o ba fe ki a ko oruko re si ara odi-iranti ninu ile Oluwa, pa ojo isinmi mo. Bi o ba fe oruko- ainipekun, ti o dara ju omo-bibi lo, je olotito si majemu Oluwa.

**Ebo ati irubo re yio se itewogba:** Olorun yio bukun awon enia ti won nfi gbogbo-ipa won se ise Oluwa; awon enia ti won nsin Oluwa ti won si nife oruko re ni ao so di pupo gidigidi. Enikeni ti ko ba ojo isinmi je, sugbon ti o di majemu re mu sinsin ni ao gbega. Awon ibukun ailegbe Oluwa yio wa si ori awon enia ti won da ara po mo Oluwa, lati sin i, ati lati fe oruko Oluwa, lati je iranse re, olukuluku eniti o pa ojo isinmi mo laiso di aimo, ti o si di majemu re mu.

Olorun yio mu won wa si oke-nla mimo re, yio si mu inu won dun, ninu ile adura re: ebo sisun won ati irubo won, yio je itewogba lori pepe re; nitori ile adura li ao ma pe ile re fun gbogbo enia **Isaiah 56: 6-7.** Bi o ba fe wa lara awon eni-ibukun Oluwa, mase so ojo isinmi di aimo. Bi o ba fe ki ebo ati irubo re se itewogba di majemu re mu sinsin.

**Ao bo o pelu ile nini Jakobu:** Awon kristiani ni lati kiyesi lili ti mbe ni igbe, bi nwon ti ndagba; nwon ki isise, beni nwon ki iranwu: a ko se Solomoni papa li oso ninu gbogbo ogo re to bi okan ninu wonyi. Nje bi Olorun ba wo koriko igbe li aso be, eyiti o wa loni, ti a si gba a sinu ina lola, melomelo ni ki yio fi le wo nyin li aso, enyin oni-kekere igbagbo? Nitorina, e mase se aniyan, wipe, "Kili ao je?" tabi "Kili ao mu?" tabi "aso wo li ao fi wo wa?" **Matteu 6: 28-31.** Eyiti o fi ye ki e ma kominu, e pa ojo isinmi mo, ki e si lo ni mimo. Bi iwo ba yi ese re kuro li ojo isinmi, lati ma se afe re li ojo isinmi Oluwa; ti iwo si pe ojo isinmi ni adun, ojo mimo Oluwa, olowo; ti iwo si bowo fun u, ti iwo ko si hu iwa re, tabi tele afe re, tabi so oro ara re. Nigbana ni inu re yio dun si Oluwa, on o si mu o gun ibi giga aiye, on o si fi ile nini Jakobu baba re bo o: nitori enu Oluwa li o ti so o **Isaiah 58: 13-14.** Mase kominu lori ohun ti iwo yio je, tabi ohun ti iwo yio mu, tabi aso ti iwo yio wo, sugbon bowo fun ojo isinmi, ki o si pa a mo: nigbana ni ao mu o gun ibi-giga aiye. Ao bukun fun o lopololopo, debipe iwo yio ma ba awon oba, awon olori orile-ede, ati awon saraki enia l'agbaiye joko papo lati jeun.

**Ao fi idi orile-ede re mule, yio si gberu:** Kiyesara, ki o si ma sora nitori ojukokoro: nitori igbesi aiye enia ki iduro nipa opo ohun ti o ni. A ko le fi ohun-ini re diwon igbesi aiye re, beni a ko le fi ohun-ini re se ipinnu aiye re **Luku 12: 15.** Niwon igbati enia ko le fi igbesi aiye re mule nipa awon ohun ini re, sora , ma pa ojo isinmi mo, ki o si lo ni mimo.

## Awon apejuwe ninu Bibeli

Awon kristiani ni lati ko eko lara awon apejuwe ti ao menuba, ki akoko to koja lo. Bi awon kristiani ba npa awon ofin ilu tabi orile-ede won mo, o di aigbodo-mase fun nwon lati pa awon ofin Oluwa fun ojo-isinmi mo.

**Awon iise Jesu Kristi ni ojo isinmi:** Awon kristiani ni lati se afarawe awon iise Jesu Kristi Oluwa ni awon ojo isinmi. Nwon ni lati mo wipe, nitori ti won wa ni alafia-ara, ni o je ki won ma sise ni ojo isinmi; ni eyiti o lodi si ofin Olorun. Nje o dara ki a se aigboran si Olorun olore-ofe ati alanu-julo, ti o fun wa ni ilera ati alafia, nipa sise ise ni ojo isinmi. A ni lati ranti pe, "igboran san ju ebo lo, ifetisile si san ju ora agbo lo" **1 Samueli 15: 22:** Nitorina, gboran si ase Oluwa, nipa pipa ojo isinmi mo ati lilo ni mimo; bikosebe o ti sote si Oluwa. Bibeli wipe, "isote dabi ese afose, ati agidi gege bi iwa buburu ati iborisa" **1 Samueli 15: 23.**

Jesu Kristi so wipe, o leto lati ma se rere li ojo isinmi, nitorina, se afarawe re nipa adura-gbigba, ati awe, ati iwasu, ati wiwo-ni-san, ati riran-ni-lowo, ati ijere okan fun Oluwa, ni ojo isinmi **Matteu 12: 12.** Tele awon apere ti Jesu fi le ile, se awon ohun daradara ti yio je iwuri fun gbogbo onigbagbo ni ojo isinmi. Jesu Kristi se opolopo ise ami ati iyanu ni **ojo isinmi**, ao si soro lori die ninu won:

- Iwosan okunrin ti owo re ro ninu sinagogu ni ojo isinmi **Luku 6: 6-10.**
- Iwosan obinrin ti o ni emi ailera ninu sinagogu ni ojo isinmi **Luku 13: 10-16.**
- Iwosan okunrin ti o ni arun asunkun ni ile okan ninu awon olori Farisi ni ojo isinmi **Luku 14: 1-4.**
- Iwosan okunrin abirun ni adagun Betesda ni ojo isinmi **Johannu 5: 1-11.**
- Imubo-sipo ati iwosan okunrin ti ko ni oju tabi iho-oju ni ojo isinmi **Johannu 9: 1-16.**
- Iwosan okunrin ti o ni emi aimo ni Kapernaumu ni ojo isinmi **Luku 4: 31-35.**

- Iwosan iya aya Peteru ni irole ojo isinmi **Luku 4: 38-39.**
- Iwosan opolopo enia nigbati orun nwo ni ojo isinmi **Luku 4: 40-41.**

Lakotan, E yipada si Olorun, ti enyin kristiani ti sote si gidigidi, nipa pipa ojo isinmi mo ati lilo ni mimo **Isaiah 31: 6.**

**Edidi: Isaiah 66: 23:** "Yio si se gbogbo eran-ara yio si wa teriba niwaju mi, lati osu titun de osu titun, ati lati ojo isinmi de ojo isinmi" li Oluwa wi.